# IHINRERE ỌMỌ ỌLỌRUN

**Romu 1:1-17; Isaiah 52:7; 61:1-3; Matteu 4:23-25; Iṣe Awọn Apọsteli 20:24; Efesu 6:18-20; 1 Tẹssalonika 1:5; 2 Tẹssalonika 1:7-10**

**ẸKỌ 380 – FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: Ẹsẹ ẹniti o mu ihinrere wá ti dara to lori awọn oke, ti nkede alafia" (Isaiah 52:7).**

### Fifihàn pe Jesu jẹ́ Ọmọ Ọlọrun

Ohun kan wà nipa ẹsin Igbagbọ́ eyi ti o yatọ si gbogbo ẹsin iyoku laye. Agbara wà ninu rẹ̀. Jesu ni "Ẹniti a pinnu rẹ̀ lati jẹ **pẹlu agbara** Ọmọ Ọlọrun, . . . . nipa ajinde kuro ninu okú." O fi hàn pe Ọmọ Ọlọrun ni Oun i ṣe nipa ṣiṣe ohun ti ẹni kan ko ṣe ri, ti ẹni kan ko si ti i ṣe lati igba naa wà. O wi pe Oun yoo fi ẹmi Oun lelẹ, Oun o si tun gba a pada; O si ṣe bẹẹ. O jí dide kuro ninu oku, ninu ara, O si wà laaye titi lae.

Nitori pe Jesu lagbara, O le fi agbara fun awọn ẹlomiran. Ọmọ-lẹyin Jesu Kristi Oluwa tootọ ni agbara lati gbé igbesi-ayé ailẹṣẹ. Ifẹ lati dẹṣẹ a maa kuro lọkan ẹni ti o ba jẹwọ ẹ̀ṣẹ ti o ti dá ti o si fi ọkàn rẹ̀ fun Jesu. Awọn ẹsin iyoku a maa kọ́ awọn eniyan lati gbé igbesi-ayé rere, ṣugbọn wọn ki i fun wọn lagbara lati ṣe ohun ti a n kọ́ wọn. Jesu nikan ni o le fun ni lagbara lati bori ẹ̀ṣẹ. Idi rẹ̀ ni yii ti Ihinrere Jesu Kristi fi ga rekọja gbogbo ẹsin.

### Iranṣẹ Kristi Kan

Paulu Apọsteli pe ara rẹ̀ ni iranṣẹ Jesu Kristi. Paulu ti jẹ́ ẹlẹsin ti o kun fun itara tẹlẹ ri. O rò pe oun n sin Ọlọrun. O ti fara balẹ kọ́ ẹkọ Bibeli Mimọ́ ti Majẹmu Laaelae, o tilẹ ti ṣe inunibini si awọn Onigbagbọ́ paapaa nitori pe o rò pe wọn tabuku si Ọlọrun nipa sisin Jesu. Ṣugbọn nigba ti a fi hàn án, nipasẹ iṣẹ-iyanu, pe ni tootọ Ọmọ Ọlọrun ni Jesu i ṣe, Messia ti a ti n reti, o fi gbogbo ọkàn rẹ̀ yipada di iranṣẹ Rẹ̀. Lẹyin eyi, o ṣe tan lati ṣe ohunkohun ti Jesu ba fẹ ki o ṣe. O ti ni iyipada ọkàn, ki i ṣe iyipada ero lasan. O gba ara rẹ̀ si iranṣẹ to bẹẹ gẹẹ ti o fi n fẹ lati fi gbogbo ayé rẹ̀ lelẹ lati sọ fun awọn ẹlomiran nipa Jesu. O ya ara rẹ̀ sọtọ fun Ihinrere, o lo aye rẹ̀ fun Ihinrere ati nikẹyin, o kú fun Ihinrere Jesu Kristi.

### Ihinrere ni Igba Laelae

Lẹyin ti oye ohun ti Ihinrere jasi ye Paulu, o mọ pe ki i ṣe ohun titun ni akoko ti rẹ̀. Lẹyin ti o ti ni iyipada ọkàn nipasẹ igbala, òye yé e pe a ti waasu Ihinrere nigba Majẹmu Laelae pẹlu.

Lati waasu Jesu Kristi Oluwa ni Ihinrere. Jesu wi pe "Abrahamu baba nyin yọ̀ lati ri ọjọ mi: o si ri i: o si yọ̀" (Johannu 8:56). O ni igbagbọ ninu Jesu, a si da a lare nipa igbagbọ naa. "Bi iwe-mimọ si ti ri i tẹlẹ pe, Ọlọrun yio dá awọn Keferi lare nipa igbagbọ, o ti wasu ihinrere ṣaju fun Abrahamu, o nwipe, Ninu rẹ li a o bukún fun gbogbo orilẹ-ède" (Galatia 3:8).

Isaiah Wolii sọ asọtẹlẹ ohun ti Ihinrere Jesu Kristi yoo jẹ́, o si kọ akọsilẹ awọn ọrọ ti Jesu yoo lò nigba ti o ba de: Oluwa "ti fi ami ororo yàn mi lati wasu ihin-rere fun awọn òtoṣi; o ti rán mi lati ṣe awotán awọn onirobinujẹ ọkàn, lati kede idasilẹ fun awọn igbekùn, ati iṣisilẹ tubu fun awọn ondè. . . . lati fi ọṣọ́ fun wọn nipo ẽrú, ororo ayọ̀ nipo ọ̀fọ, aṣọ iyin nipo ẹmi ibanujẹ" (Isaiah 61:1-3).

### Ihinrere Ifẹ

Ihinrere Jesu Oluwa jẹ́ iroyin rere. Jesu mú alaafia, aanu, ayọ ati iyọnú wa. Ẹsin awọn Keferi jẹ́ ẹsin ikorira. Awọn ti n hu iwa àjẹ́ a maa fi ailaanu já ọmọde gba lọwọ iya rẹ wọn a si pa a lati fi ṣetutu fun oriṣa wọn ti o n binu. Nigba miiran bi ọkunrin ba kú, wọn a sun iyawo rẹ̀ ninu ina pẹlu òkú ọkọ rẹ tabi ki wọn fi ipa mu awọn opó lati pa ara wọn ki ẹmi wọn ba le tẹle ẹmi ọkọ wọn ti o kú, gẹgẹ bi ẹ̀kọ ti awọn ti n hu iwa àjẹ́ fi lelẹ. Wo iru iwa ika ati ibanujẹ nla ti o jẹ́ ipin awọn ti o wà ninu okunkun laimọ Ọlọrun.

Isaiah Wolii wi pe: "Ẹsẹ ẹniti o mu ihinrere wá ti dara to lori awọn oke, ti nkede alaafia; ti nmu ihin rere ohun rere wá, ti nkede igbala" (Isaiah 52:7). Ronu iru iyipada ti o wà ninu igbesi-ayé awọn Keferi ti o ti wà ninu kiki okunkun ati iwa ika, ti wọn si gbọ́ pe Jesu fẹran wọn, ati pe yoo fun wọn ni ayọ ati ifẹ ninu ọkàn wọn pẹlu. Wo bi ẹni ti o mú ihin igbala wa fun wọn yoo ti dara tó, igbala alaafia naa ti Jesu wi pe yoo jẹ́ ti gbogbo eniyan!

**Fun Gbogbo Eniyan**

Paulu Apọsteli wi pe awọn eniyan yoo wà ti yoo gbọran si igbagbọ naa "lãrin gbogbo orilẹ-ède, nitori orukọ rẹ̀" (Romu 1:5). Awọn eniyan wa ni gbogbo orilẹ-ede ti a o gbala bi ẹni kan ba sọ fun wọn nipa Jesu.

Nigba miiran awọn eniyan ti o wa ni ipinlẹ Ila-oorun ayé a maa rò pe ẹsin igbagbọ jẹ́ ẹsin ilẹ Amẹrika. Ṣugbọn Jesu kò gbé ni ilẹ Amẹrika. Bẹẹ ni ako tilẹ ti i wá awari ilẹ Amẹrika nigba ti Jesu wa laye. Ṣugbọn O paṣẹ fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ lati lọ si gbogbo ayé, lati waasu Ihinrere. Nitori naa bi ọdun ti n rekọja lọ, awọn oloootọ ajihinrere n lọ si iwọ-oorùn, awọn ti o kọkọ tẹ orilẹ-ède Amẹrika dó si dé sibẹ ki wọn ba le ni anfaani ati sin lai si idiwọ. Nitori pe a fi Eto-ijọba orilẹ-ede yii lelẹ lori ẹkọ Bibeli, ẹsin Igbagbọ tàn ká gbogbo ilẹ Amẹrika; awa pẹlu si ti rán awọn ajihinrere lọ si orilẹ-ede miiran. Ọlọrun bukun orilẹ-ede yii fun iduro Igbagbọ rẹ; ṣugbọn bi ọkàn awọn eniyan ba n yipada sibẹ kuro lọdọ Ọlọrun gẹgẹ ti o ti n ri ni lọlọọ yii, idajọ Ọlọrun yoo wá sori ilẹ Amẹrika.

**Awọn Onigbagbọ́ ti Romu**

Paulu Apọsteli kọwe si awọn Onigbagbọ ti o wà ni Romu. Awọn diẹ jẹ́ Ju, ṣugbọn ijọ kan wa nibẹ pẹlu ti i ṣe ti awọn Keferi. Wọn ni igbagbọ́ ti o le to bẹẹ ninu Jesu ti a fi gbọ́ nipa igbagbọ wọn jakejado gbogbo ayé ti a mọ nigba naa. Wọn kò bẹru lati jẹ ki imọlẹ wọn ki o tàn fun Jesu. Wọn fẹ ki ayé ki o mọ pe Jesu n gba ni kuro ninu ẹ̀ṣẹ. Iṣẹ wọn laye ni eyi.

Paulu ti kọwe kan si wọn, ṣugbọn oun pẹlu n fẹ lati lọ bẹ̀ wọn wò. O sọ pe itunu ni o jẹ fun oun lati wà pẹlu awọn eniyan ti wọn gbagbọ bi ti rẹ̀. Gbogbo wa ni a le ri agbara gba kun agbara nigba ti a ba pade ti a si n sọ ohun ti Oluwa ṣe fun wa.

Paulu jẹ alufaa ati ajihinrere laaarin wọn, o si mọ pe oun yoo jẹ́ iranlọwọ fun wọn nipa ti ẹmi. Ṣugbọn oun ko gba pe oun ti mọ ohun gbogbo. O gba pe oun naa pẹlu le ri ẹkọ kọ́ lara wọn.

**Igbẹkẹle Paulu ninu Ihinrere**

Wo o bi Paulu Apọsteli ti fẹran Ihinrere Jesu Kristi Oluwa tó! O n fẹ lati waasu rẹ̀ ni Romu, bi o tilẹ jẹ pe eyiyi yoo mu ki o jiya. Ko si ohun kan ti o da a duro ninu ilepa rẹ̀ lati gbé orukọ Jesu ga ati lati sọ fun awọn ọkunrin ati obinrin pe a le gbà wọn là. Ko tiju lati sọ fun awọn eniyan nipa Jesu, nitori pe o mọ pe a le gba wọn la kuro ninu ẹ̀ṣẹ wọn nipasẹ Orukọ yii. Paulu ko ṣiyemeji lati sọ fun wọn pe, "A kò le ṣe alaitun yin bi." O mọ pe wọn le ni iyipada ọkàn, ati pe wọn yoo mọ̀ nigba ti iyipada yii ba ṣẹlẹ, wọn yoo si mọ̀ pe igbala wa fun ẹnikẹni ti o ba le san ohun ti yoo gba a lati ri i gbà.

Bi a ba ti dari ẹ̀ṣẹ wa ji wa ti a si n gbadun igbala Oluwa, a le sọrọ pẹlu idaniloju. A le sọ gẹgẹ bi Johannu Apọsteli ti sọ ni ọpọlọpọ igba: "Awa mọ. . . ." Awa mọ̀ pe a ti rekọja lati inu iku si iye. Awa mọ pe a di ẹda titun ninu Kristi Jesu. Awa mọ pe awọn ẹ̀ṣẹ wa ti lọ. Awa mọ pe Oludande wa n bẹ. Awa mọ pe Jesu tun n pada bọ̀ lẹẹkeji.

**Irin Wa nipa Igbagbọ́**

Nipa oore-ọfẹ ni a ti fi gba wa là, ki i ṣe nipa iṣẹ. Ko si ohun rere kan ti a ṣe ti o le ra ipo kan fun wa ni Ọrun. Ọna kan ṣoṣo ni o wà ti a le gba ri igbala: "Olododo yio wà nipa igbagbọ." A ni lati ronupiwada awọn ẹ̀ṣẹ wa ki a si gbà pe Jesu ni Ọmọ Ọlọrun Ẹni ti O le dariji ti O si n dariji. Iṣẹ rere yoo jẹ́ eso gbigba ti a gbà wa la nipa igbagbọ́.

Ibẹrẹ irin wa nipa igbagbọ ni igbala jẹ́. Ohun gbogbo ti a n gba lọdọ Ọlọrun ni lati wá nipasẹ igbagbọ́. Lẹyin ti a ti gba wa la (tabi ti a da wa lare nipa igbagbọ́), a ni lati wá isọdimimọ -- a si maa n ri eyi gba pẹlu, nipa igbagbọ́. Eyi a naa ṣẹlẹ lẹsẹ kan naa ti a ba ti fi ara wa rubọ fun Ọlọrun jinlẹ ju ti atẹyinwa lọ ti a si gbagbọ pe O ti dahun adura wa.

Nigba ti a ba ṣaisan, a o gbadura a o si gbagbọ́ pe Jesu mu wa lara da, bẹẹ ni a o si ri iwosan gba fun ara wa. Ohunkohun ti Onigbagbọ ba n ṣe, o ni lati ṣe e pẹlu ọkàn yii pe Jesu ni inu didun si i. "Gbogbo ẹbun rere ati gbogbo ẹbun pipe lati oke li o ti wá, o si n sọkalẹ lati ọdọ Baba imọlẹ wá" (Jakọbu 1:17). O fẹ lati fi ẹbun rere fun awọn ọmọ Rẹ̀. Ṣugbọn "li aisi igbagbọ ko ṣe iṣe lati wu u" (Heberu 11:6). Lonii lọfẹ ni a fi Ihinrere fun wa. A le gba a, a si le kọ̀ ọ́: a le yan eyi ti o wu wa. Ṣugbọn akoko naa n bọ ti a o jẹ awọn ti o kọ Ihinrere silẹ niya. Nigba ti Jesu yoo pada wa pẹlu awọn angẹli Rẹ̀, Oun yoo gbẹsan lara awọn "ti kò mọ Ọlọrun, ti nwọn kò si gba ihinrere Jesu Oluwa wa gbọ." Ṣugbọn awọn ti o ti fi ọkan wọn fun Un yoo gbadun iye ainipẹkun. Ogo ti o ti bẹrẹ ninu ọkan wa nihin yoo maa pọ si i siwaju ati siwaju titi ayeraye.

**AWỌN IBEERE**

1 Ki ni itumọ Ihinrere?

2 Sọ ọna kan ti Kristi gba fi hàn pe Ọmọ Ọlọrun ni Oun i ṣe? Gẹgẹ bi a ti kọ ọ silẹ ninu Romu ori Kin-in-ni.

3 Ọna wo ni Ihinrere Jesu Kristi fi yatọ si awọn ẹsin miiran?

4 Ki ni Isaiah sọ nipa ẹsẹ ẹni ti o mú ihinrere wá?

5 Awọn wo ni Jesu n fẹ ki Ihinrere jẹ́ ti rẹ̀?

6 Bawo ni Paulu Apọsteli ti fi ara rẹ̀ fun Ihinrere tó?

7 Bawo ni a ṣe n ri nnkan gbà lọdọ Ọlọrun?